Ọrọ yẹn ninu ododo ti alujannu n ji gbọ ni o wa, yoo waa gbe e si eti aayo rẹ gẹgẹ bi adiyẹ ṣe maa n gbe ọrọ fun adiyẹ miran, nigba naa ni wọn o waa ro irọ to le ni ọgọrun-un mọ ọn

Lati ọdọ ‘Āisha – ki Ọlọhun yọnu si i– o sọ pe: Awọn eeyan kan bi Ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – leere nipa awọn adagbigba, ni Ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wa sọ fun wọn pe: «Wọn o jẹ nkankan» wọn sọ pé: Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, dajudaju wọn maa n sọ awọn nkan ni igba miran ti yio si jẹ ododo, ni Ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wa sọ pe: «Ọrọ yẹn ninu ododo ti alujannu n ji gbọ ni o wa, yoo waa gbe e si eti aayo rẹ gẹgẹ bi adiyẹ ṣe maa n gbe ọrọ fun adiyẹ miran, nigba naa ni wọn o waa ro irọ to le ni ọgọrun-un mọ ọn».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Wọn bi Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – leere nipa awọn ti wọn maa n sọ nipa awọn kọkọ ti yio ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju, ni o wa sọ pe: Ẹ ma bikita pẹlu wọn, Ẹ si ma di ọrọ wọn mu, alamọri wọn o si gbọdọ pataki si yin. Ni wọn wa sọ pe: Dajudaju ọrọ wọn maa n ṣe deedee nkan ti n ṣẹlẹ ni igba miran, gẹgẹ bii ti wọn ba sọ nipa iṣẹlẹ alamọri kọkọ kan ni oṣu bayii ni ọjọ bayii, ti yio si ṣẹlẹ ni ibamu si ọrọ wọn. Ni o wa sọ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – pe: Dajudaju awọn alujannu maa n ji awọn iroyin sanmọ gbọ, nigba naa ni wọn yio wa sọkalẹ wa ba awọn aayo wọn ninu awọn adagbigba ti wọn o si fun wọn ni iro nkan ti wọn gbọ, léyìn naa ni adagbigba o fi irọ ọgọrun-un kun eyi ti o gbọ lati sanmọ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/8918